# Ète Ìṣewẹ́kú nínú Ìwé-Ìtàn Àròsọ *Ó le kú*

**Ọlakolu, Oluwatoyin Titilayọ**
*Adeyemi College of Education, Ondo, Ondo state*
*08067392364, tititoyin@gmail.com*

**Àṣamọ̀**

Ìṣewékú jẹ́ ìbáṣepọ̀ tó ń farahàn ní ìpele sẹ̀mańtíìkì nígbà tí a bá ń ṣafọ̀, èyí tí ó máa ń so àwọn fọ́nrán inú gbólóhùn pọ̀ lati di odidi. Àfojúsùn pépà yìí ni láti ṣàgbéyẹ̀wò bí àgbékalẹ̀ ìṣewẹ́kú nínú Halliday and Hasan (1976) (pàápàá ète ìṣewẹ́kú) ṣe wú lò fún ìtumọ̀, òye àti ìṣọ̀kan àwọn fọ́nrán ìhun nínú àwọn ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá nípa lílo *Ó le kú* ti Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ gẹ́gẹ́ bi ìtọ́kasí. Àwọn gbólóhùn inú ìwé ìtàn-àròsọ yìí ni a lò fún déétà-fáyẹ̀wò wa. A fa déétà-fáyẹ̀wò wọ̀nyí jáde nípa kíka ìwé ìtàn àròsọ náà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà lati ṣàkíyèsí onírúurú ète ìṣewẹ́kú tí òǹkọ̀wé ṣàmúlò nínú ìwé náà àti ipa àwọn ète wọ̀nyí lórí ìtumọ̀ ìwé náà. Nínú pépà yìí, a wo ìtọ́kasí, ìgékúrú àti ìsopọ̀ gẹ́gẹ́ bí ète ìṣewẹ́kú. Àwọn ète ìṣewẹ́kú tí a ṣàfihàn wọn yìí máa ń mú kí àkójọpọ̀ gbólóhùn nínú iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ ní ìṣewẹ́kú tí kò fi ní dàbí pé wọ́n kàn ń jẹyọ bí ó ti wù wọ́n. Àbájáde ìwádìí yìí fihàn pé òǹkọ̀wé lo ète ìgékúrú àti ìtọ́kasí láti dín àwítúnwí kù nínú ìtàn náà, èyí mú kí gbogbo àwọn gbólóhùn inú ìwé náà ṣe wẹ́kú. Àwọn ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ni òǹkọ̀wé lò láti so ọ̀rọ̀, àpólà, awẹ́ gbólóhùn àti odidi gbólóhùn pọ̀ láti fún ìtàn náà ní àrògún àti ìtumọ̀. Àbájáde iṣẹ́ yìí fi Akínwùmí Ìṣọ̀lá hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tó ní ìmọ̀-ọ́n-ṣe ìmédèlò nítorí pé ó lo oríṣiíríṣìí sítáì láti gbé kókó inú ìwé ìtàn àròsọ *Ó le kú* jáde sí àwọn òǹkàwé.
***Ọ̀rọ̀ Atọ́nisọ́nà:*** *Ìṣewẹ́kú, ìgékúrú, ìsopọ̀, ìtọ́kasí, ète ìṣewẹ́kú.*

**Abstract**

Cohesion is a relation that occurs on the semantic level of communication which links sentential elements together into a unified whole. There are several cohesive relations that link the sentences into a text. The essence of this study is to examine the extent to which Halliday and Hasan (1976) model of cohesion (precisely cohesive devices) is used to achieve unity, meaning, understanding and readability in Yoruba literary texts, using Ó le kú as a case-study. Ó le kú is a prose text written by Akinwumi Isola, a renowned Yoruba literary artist. The data for the study consisted of Yoruba sentences selected from the novel. The data was extracted from the novel by reading through the text severally to note the different types of cohesive devices used by the author and their effect on the interpretation of the text. The paper investigates the extent to which the author of Ó le kú uses the textual resources of cohesion and cohesive devices to link ideas in the sentences used in the text and examines the effect that the cohesive devices used have on the quality of message passed across in the novel. In this paper, we deal with reference, ellipsis and conjunction. These mechanisms of cohesion, common to all languages, make a series of sentences coherent, so they do not seem to occur randomly. The purpose of ellipsis and reference is to avoid the burdening repetitions within the text, and to make the whole text cohere. Coordinating conjunctions were used as joining or linking devices in the text. The author based on the outcome of the study used intermixed styles to convey his message to the readers.
***Keywords:*** *Cohesion, ellipsis, conjunction, reference, cohesive devices*

## Ìfáárà

Èdè ní í ṣe pẹ̀lú àkójọpọ̀ gbólóhùn àti ìsọ tí ó so pọ̀ mọ́ ara wọn. Nítorí ìdí èyí, ìṣewẹ́kú ni a lè pè ní èròjà a-so-ọ̀rọ̀-pọ̀. Bí a bá ní àyọkà kan ṣe wẹ́kú, ó túmọ̀ sí pé ó so pọ̀ mọ́ ara wọn láti gbólóhùn kan sí òmíràn, àti láti ìpínrọ̀ kan sí èkejì. A máa ń so gbólóhùn pọ̀ nípa lílo àwọn ète-àsopọ̀. Lára ohun tó jẹ ìtúpalẹ̀ ajẹmọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè lógún ni ìtúpalẹ̀ àtòpọ̀ gbólóhùn

láti lè ní òye bí ìtumọ̀ ṣe ń farahàn nínú àyọkà. Àyọkà, yálà alohùn tàbí àkọsílẹ̀, máa ń ní ìtumọ̀ nígbà tí gbogbo ìhun rẹ̀ bá kóra jọ pọ̀ láti di odidi kan. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Òsísanwó (2005:31) pé: "a text is said to be cohesive when the linguistic means by which a text function is held together as a single unit."

> Àyọkà máa ń ní ìṣewẹ̀kú nígbà tí àwọn ohun èlò ajẹmọ́-ẹ̀dá-èdè tí ó ń mú kí àyọkà ṣiṣẹ́ tí ó yẹ bá wà ní ìṣọ̀kan gẹ́gẹ́ bí ẹyọ kan.

A máa ń ṣàmúlò àwọn ète-ìṣewẹ̀kú láti so gbólóhùn àti ìpínrọ̀ pọ̀. Peterson àti McCabe (1991) náà fara mọ́ èrò yìí nípa kíka ìṣewẹ̀kú mọ́ àwọn èròjà mẹ́ta tó ń mú kí ìtàn àròsọ yéni yékéyéké. Wọ́n ṣàlàyé pé:

> "there are three aspects of a narrative that make it comprehensible: content, cohesion and staging".
> *Ẹ̀yà mẹ́ta nínú ìtàn àròsọ ni ó máa ń mú kí ó yéni yéké: àkóónú, ìṣewẹ̀kú àti àgbékalẹ̀.*

Ìṣewẹ̀kú ní èrò Pèterson àti McCabe (1991) ni àjọṣepọ̀ tó ní ìtumọ̀ láàárín àwọn gbólóhùn. Wọ́n tún ṣàkíyèsí síwájú sí i pé àṣàyàn àgbékalẹ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àti ẹni tó ṣe àgbékalẹ̀ wọn ni ó máa ń mú kí ìtàn ní ìṣewẹ̀kú kí ó sì yé ni. Àwọn ète ìṣewẹ̀kú yìí ni ó máa ń so àwọn fọ́nrán inú ìtàn pọ̀ lọ́nà tí yóò gbà ní ìtumọ̀. Bákan náà, ète ìṣewẹ̀kú yìí kan náà ni ó máa ń mú kí gbogbo agbọn ìtàn àròsọ ní ìbáṣepọ̀ tí ó ṣe é ṣe kí ó sọnù láàárín wọn.

Àfojúsùn pépà yìí ni láti ṣe ìwádìí bí àgbékalẹ̀ ìṣewẹ̀kú nínú Halliday & Hasan (1976) àti ète ìṣewẹ̀kú ṣe wúlò fún ìṣàfihàn ìtumọ̀, òye àti ìṣọ̀kan àwọn fọ́nrán ìhun nínú àwọn ìwé ìtàn àròsọ Yorùbá nípa lílo ìwé-ìtàn àròsọ *Ó le kú* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ gẹ́gẹ́ bí òdiwọ̀n. Pépà yìí ṣàgbéyẹ̀wò bí òǹkọ̀wé ìwé ìtàn àròsọ náà ṣe lo àwọn èròjà ìṣewẹ̀kú àti ète rẹ̀ láti so èrò inú ìtàn náà pọ̀. Bákan náà ni ó tún wo ipa àwọn ète ìṣewẹ̀kú náà lori ìwé náà.

## Tíọ́rì Ìṣàmúlò

Tíọ́rì tí a lò fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí ni tíọ́rì Gírámà ajẹmọ́-ìlò (Functional Grammar) tí Halliday jẹ́ agbátẹrù rẹ̀. A tún ṣàmúlò ìṣewẹ̀kú nínú Halliday àti Hasan (1976) àti Halliday and Mathiessien (2014) fún ìtúpalẹ̀ *Ó le kú*. Ní èrò tiwọn, ó ṣe é ṣe kí ìṣewẹ̀kú jẹ́ ajẹmọ́-gírámà tàbí ẹlẹ́yọ-ọ̀rọ̀. Ìtọ́kasí, ìfirọ́pò àti ìgékúrú, pẹ̀lú ìsopọ̀ jẹ́ ẹ̀yà ìṣewẹ̀kú ajẹmọ́-gírámà nítorí pé wọ́n ní ṣe pẹ̀lú ìhun síntáàsì nígbà tí ìṣewẹ̀kú ẹlẹ́yọ-ọ̀rọ̀ ń tọ́ka sí ète lílo ọ̀rọ̀ tí ó jọra nínú gbólóhùn ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé. Ìṣewẹ̀kú ajẹmọ́-gírámà nìkan ni pépà yìí ṣàgbéyẹ̀wò.

Tíọ́rì Gírámà ajẹmọ́-ìlò tí a ṣàmúlò yìí rí èdè gẹ́gẹ́ bí i ìhùwàsí tí ó ní ìwúlò tàbí iṣẹ́ tó ń ṣe fún àwùjọ. Tíọ́rì yìí máa ń wo bí a ṣe lo èdè, ìdí tí a fi lò ó àti bí ó ṣe bá ìṣẹ̀lẹ̀ kan mu. Ọ̀kẹ́ àìmọye ìwúlò èdè ni a lè tọ́ka sí, àmọ́ Halliday àti Mathiessien (2014) ti ṣàfihàn ìlò èdè mẹ́ta gbòógì. Àwọn ni:

**Ìlò Asọ̀rírí:** Ìlò-èdè yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé a lè lo èdè fún àgbékalẹ̀ èrò àti ìrírí olùsọ tàbí òǹkọ̀wé nípa lílo èdè láti sọ ìrírí rẹ̀ nínú ayé àti nínú èrò rẹ̀. Ìlò èdè yìí máa ń jẹyọ nípasẹ̀ àwọn akópa (participants), ìṣẹ̀lẹ̀ (process) àti àfikún (circumstance).

Ìlò afìbáṣepọ̀-hàn: Ìlò èdè yìí ní ṣe pẹ̀lú ṣíṣe àfihàn àjọṣepọ̀ tó wà láàárín àwọn akópa tó ń ṣafọ̀. Ìlò-èdè yìí ni à ń lò fún ìbáṣepọ̀ láàárín ara wa, láti bèèrè ìbéèrè, láti pàṣẹ, láti fi ìdí ọ̀rọ̀ kan múlẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìlò èdè afìbáṣepọ̀-hàn yìí ń mú kí ìbáṣepọ̀ tí ó fẹsẹ̀múlẹ̀ wà láàárín àwọn akópa tó ń ṣafọ̀, èyí yóò sì fún akópa kan ní àǹfàní láti fún akópa mìíràn ní ojúṣe bí i bíbèèrè, dídáhùn, títakò, gbígbọ́yé abbl.

**Ìlò ìṣewẹ́kú afọ̀:** Ìlò èdè yìí ni à ń lò láti fi sẹ̀dá afọ̀ yálà èyí tí a kọ sílẹ̀ tàbí tí a sọ lẹ́nu, Nípasẹ̀ ìlò-èdè yìí ni ìbáṣepọ̀ tó lọ̀ọ̀rìn fi máa ń wà láàárín òǹkọ̀wé àti òǹkàwé. Ìlò-èdè kẹta yìí ni ó máa ń mú ìbáṣepọ̀ wà láàárín àwọn gbólóhùn tó wà nínú ìwé tí ó sì máa ń ṣàfihàn bí wọ́n ṣe ṣe wẹ́kú sí. Halliday (2014) jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé ìwúlò-èdè mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí ni ó farakọ́ra nínú èdè àti pé àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ni wọ́n jọ ń ṣiṣẹ́ pọ̀. Fún iṣẹ́ yìí, apá kan ìlò-èdè kẹta tí ó ní ṣe pẹ̀lú ìṣewẹ́kú ni a ó ṣàmúlò.

## Ìṣewẹ́kú

Halliday àti Hasan (1976) sọ pé:

> Cohesion is recognized when the interpretation of some elements in the discourse is dependent on that of another. It refers to the resources within language provided by clause structure and clause complexes.
>
> A lè dá ìṣewẹ́kú mọ̀ nígbà tí ìtumọ̀ àwọn fọ́nrán kan nínú afọ̀ bá dá lórí àwọn fọ́nrán mìíràn nínú afọ̀ kan náà. Ìṣewẹ́kú ń tọ́ka sí àwọn èròjà inú èdè tí ó ń jẹyọ nínú ìhun àwẹ́ gbólóhùn.

Halliday (2014) ní tirẹ̀ sọ pé ìṣewẹ́kú ń tọ́ka sí àwọn èròjà inú èdè tí a lè bá pàdé nínú ìhun awẹ́ gbólóhùn àti ìpele tí ó ju awẹ́ gbólóhùn lọ tí ó ń mú kí ìsopọ̀ wà láàárín afọ̀. Ìṣewẹ́kú túmọ̀ sí bí ìbáṣepọ̀ láàárín ìkójọpọ̀, ìsopọ̀ àti ìtayọ ṣe ṣe rẹ́gí sí (Òjó 2016). Ó ní ṣe pẹ̀lú bí àwọn èrò ṣe ṣe rẹ́gí sí ní ìpele gbólóhùn nínú afọ̀. Bákan náà ni ó tún ń tọ́ka sí ìbáṣepọ̀ àwọn ìtumọ̀ nínú afọ̀ tí a fi ń pè é ní afọ̀. Halliday àti Hasan (1976) ṣàlàyé síwájú sí i pé ìṣewẹ́kú máa ń ṣàfihàn ìtẹ̀síwájú tó wà láàárín apá kan nínú afọ̀ àti àwọn apá tó kù. Ohun tí ó jẹ ìṣewẹ́kú lógún ni ìbáṣepọ̀ láàárín ìtumọ̀ nínú afọ̀ èyí tí a ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀ pẹ̀lú ìrísí gbólóhùn.

Ìṣewẹ́kú ṣe pàtàkì sí òǹkàwé láti lè hun ìtumọ̀ jáde nínú afọ̀ àti fún òǹkọ̀wé láti sẹ̀dá afọ̀ tí ó lè tètè yéni yékéyéké. Ìṣewẹ́kú máa ń wáyé nínú afọ̀ nípa lílo àwọn ète asọ̀rọ̀pọ̀ (a-so-ọ̀rọ̀-pọ̀) nínú gbólóhùn. Connor (1984) ki ìṣewẹ́kú gẹ́gẹ́ bí "ìlò àwọn ète-ìṣewẹ́kú tó fojúhànde èyí tí ó máa ń fi ìbáṣepọ̀ hàn láàárín àwọn gbólóhùn àti apá kan ara afọ̀. Ó máa ń mọ àwọn ọ̀nà tí gbogbo ìhun inú afọ̀ fi so pọ̀ mọ́ ara wọn láti di odidi afọ̀ kan. Ìṣewẹ́kú máa ń fi àyè gba ìtẹ̀síwájú láàárín apá kan afọ̀ àti àwọn apá tó kù. Ìtẹ̀síwájú afọ̀ yìí wúlò fún òǹkàwé láti ṣàwárí gbogbo ohun tí ó nílò fún ìtumọ̀ afọ̀. Pépà yìí rí ìṣewẹ́kú gẹ́gẹ́ bí ìbáṣepọ̀ tó ń wáyé ní ìpele sẹ̀mańtíìkì afọ̀ èyí tí ó ń so àwọn fọ́nrán gbólóhùn pọ̀ láti di odidi.

Ète ìṣewẹ́kú mẹ́ta ni a ó ṣàgbéyẹ̀wò nínú pépà yìí: Ìtọ́kasí, ìgékúrú àti ìsopọ̀. A ó ṣàlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kan lérèfé nípa wíwo àpẹẹrẹ láti inú *Ó le kú*.

**Ìtọ́kasí**

Èyí ni àwọn ọ̀rọ̀ tí ìtumọ̀ wọn máa ń farahàn nípa títọ́ka padà sí àwọn ọ̀rọ̀ mìíràn nínú afọ̀. Halliday àti Hasan (1976) ki ìtọ́kasí gẹ́gẹ́ bí 'ẹ̀yà ète-ìṣewẹ́kú kan níbi tí fọ́nrán lìǹgúísíìkì wọ̀nyí, ní ìwòye Fontaine (2013) máa ń tọ́ka sí nǹkan mìíràn fún ìtumọ̀ wọn. Ìyẹn ni pé, àwọn ìpèdè yìí máa ń fa ìtumọ̀ wọn jáde láti ibò mìíràn. Ìtọ́kasí ni a tún lè kì gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà ìṣewẹ́kú tí ó ní ìtumọ̀ kan ní pàtó fún àwọn kókó tó ń tọ́ka sí. Àwọn ìtumọ̀ yìí máa ń jẹyọ látàrí ọ̀gangan sàkání tí a bá ti rí ìtọ́kasí. Bákan náà, ó yẹ kí fọ́nrán tí à ń tọ́ka sí ní àbùdá sẹ̀máńtíìkì tí ó fara jọ ti fọ́nrán tí ó ń tọ́ka sí i. Àbùdá yìí lè jẹ́ ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ kan náà.

Ẹ̀yà ìtọ́kasí méjì ni ó wà: Ìtọ́kasí alórí, níbi tí ìtumọ̀ àwọn fọ́nrán ti máa ń jẹyọ láàárín afọ̀ àti ìtọ́kasí aílàlórí, níbi tí ìtumọ̀ ti máa ń farahàn nínú sàkání afọ̀, yàtọ̀ sí afọ̀ gan-an fúnra rẹ̀. Nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí, gbogbo àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ ni ó jẹ́ àpẹẹrẹ ìtọ́kasí:

> 1. Àjàní ń wá ẹ̀rọ agbọ̀rọ̀sọ tí àròfọ̀ náà wà, Ó ní, níjọ́ tí Àṣàkẹ́ alára kọ́kọ́ gbọ́ àròsọ yìí, ọjọ́ lọjọ́ náà (1). Mo kàn sọ fún un pé kí ó fetísílẹ̀ ni ò(2). Mo wá tẹ ẹ̀rọ náà(3). Ó farabalẹ̀, ó wá ń ṣẹ́jú pẹ́pẹ́, ó ń rẹ́rìn-ín músẹ́, èmi náà jókòó, mo tẹjúmọ́ ọn. (4) Nígbà tí ó gbọ́ ọ tán, ó wá wò mí lójú, inú rẹ̀ dùn gan-an.(5) Ni a bá dìmọ́ ara wa. (6).Àwọn obìnrin ń fẹ́ àpọ́nle o.(7). Ó yá, máa gbọ́ ọ.(8)
> (o.i 19-20)

Fún àpẹẹrẹ, ìlò *mo*, *èmi* àti *ó* nínú àyọlò òkè yìí jẹ́ àpẹẹrẹ ìtọ́kasí alórí tó dúró gẹ́gẹ́ bí afárá láàárín afọ̀ àti ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀. Kò sí bí a ṣe lè mọ ẹni tí arọ́pò-orúkọ *ó* ń tọ́ka sí láì mọ ẹni tí à ń bá sọ̀rọ̀. Ẹ̀wẹ̀, *mo* àti *èmi* kò ní ìtumọ̀ kankan láì mọ ẹni tó ń sọ̀rọ̀. Àpẹẹrẹ ìtọ́kasí aláìlórí ẹyọ kan ni a rí tọ́ka sí nínú àyọlò òkè yìí. Àpẹẹrẹ náà ni 'àwọn' nínú gbólóhùn kéje nígbà tí Àjàní sọ pé 'Àwọn obìnrin ń fẹ́ àpọ́nlé o'. Arọ́pò-orúkọ yìí kò ní ìtumọ̀ kankan fún ra rẹ̀ yàtọ̀ fún pé ó ń fi ọ̀pọ̀ hàn. Àwọn arọ́pò-orúkọ yìí jẹ́ ẹ̀yà ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ awẹ̀yìn. Ní gbólóhùn àkọ́kọ́, *ó* tọ́ka padà sí Àjàní. *Mo,* ní gbólóhùn kejì, kẹta àti ìkẹ́rin sì ń tọ́ka padà sí Àjàní nígbà tí *un* ní gbólóhùn kejì ń tọ́ka sí Àṣàkẹ́ tí a ti kọ́kọ́ mẹ́nubà ní gbólóhùn àkọ́kọ́. Arọ́pò-orúkọ *ó* tí ó wáyé ní ẹ̀ẹ̀mẹ́ta ní gbólóhùn kẹrin àti ìkárùn-ún ń tọ́ka padà sí Àṣàkẹ́. Ní gbólóhùn karùn-ún àyọlò yìí, arọ́pò-orúkọ *mi* àti *rẹ* ń tọ́ka padà sí Àjàní àti Àṣàkẹ́.

Olú-ẹ̀dá ìtàn inú àyọlò yìí ni a kọ́kọ́ ṣàfihàn rẹ̀ nípa lílo orúkọ rẹ̀, èyí fún òǹkàwé ní àǹfàní láti fìdí ẹ̀dá-ìtàn yìí múlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí kókó kan gbòógì nínú ìtàkùn ìtumọ̀ tí a lè fún ìtàn àròsọ. Lẹ́yìn èyí, òǹkọ̀wé wá bẹ̀rẹ̀ sí ní ṣe àfihàn Àjàní nípa lílo arọ́pò-orúkọ *ó*, *mo*, *èmi* àti *mi*. Àwọn wọ̀nyí jẹ́ àpẹẹrẹ ìtọ́kasí, èyí tí ó dàbí ìdánimọ̀ fún ẹ̀dá-ìtàn, Àjàní nípa títọ́ka padà sí i nínú gbólóhùn àkọ́kọ́. Ẹ̀yà ìṣewẹ́kú yìí ń ṣiṣẹ́ awẹ̀yìn, èyí tó ń fikún ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín gbólóhùn àti ìtumọ̀ wọn lódidi. Nítorí ìdí èyí, a lè sọ pé àtòpọ̀ gbólóhùn ló ń di afọ̀. Kò ṣe é ṣe láti fún àwọn ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ inú àyọlò yìí ní ìtumọ̀ láì wo ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ àti arọ́pò-orúkọ inú gbólóhùn kìíní, ìkejì àti ìkẹ́ta.

Iṣẹ́ méjì pàtàkì ni ète ìtọ́kasí ṣe nínú *Ó le kú*: àkọ́kọ́ ni pé a lò ó fún ìṣọ̀kan ìtàn àròsọ náà. Èkejì ni pé ète yìí ran òǹkọ̀wé lọ́wọ́ láti dín àwítúnwí kù nínú iṣẹ́ ọnà náà, nítorí pé kò nílò láti tún máa dárúkọ ẹ̀dá ìtàn kan náà ní gbogbo ìgbà.

**Ìgékúrú**

Ètò mìíràn tí a tún lè lò fún ìṣewẹ́kú àyọkà tí ó wúlò fún pépà yìí ni ìgékúrú. Ìgékúrú jẹ́ ọ̀nà tí a lè gbà fi ìdí ìbátan ajẹmọ́ sẹ̀máńtíìkì múlẹ̀ nípa lílo fọ́nrán-gírámà. Ní ṣókí, ìgékúrú jẹ́ èrò tí ó gbajúgbajà pé ohun kan tí a ò sọ… a ò sọ ọ́ ṣùgbọ́n síbẹ̀ ó yé wa (Halliday àti Hasan 1976). Ìgékúrú dúró fún fífo àwọn fọ́nrán kan tàbí ìfirọ́pò òfo. Àwọn fọ́nrán tí a fò yìí jẹ́ àwọn tí a ti mẹ́nubà ṣáájú. Ìyẹn ni pé, a fo apá kan nínú gbólóhùn pẹ̀lú èrò wí pé gbólóhùn ìṣáájú á tan ìmọ́lẹ̀ sí ìtumọ̀ gbólóhùn náà. Ní àfikún, ìgékúrú jẹ́ ìbátan láàárín àyọkà, fọ́nrán tí a fò ti kọ́kọ́ jẹ yọ nínú gbólóhùn tí ó ṣáájú. Ní èrò Halliday àti Hasan (1976) nínú Fontaine (2013), "ìgékúrú máa ń wáyé nígbà tí a bá kọ̀ láti sọ ohun kan tí ó wúlò fún ìhun gbólóhùn kan". Wọ́n ṣàlàyé sí i pé ìgékúrú máa ń mú ìṣewẹ́kú lọ́wọ́ nítorí pé ó máa ń mú kí ìsopọ̀ wà láàárín agbọn ìgékúrú kan àti àwọn apá gbólóhùn tó kù. Fontaine (2013) ní tirẹ̀ rí ìgékúrú gẹ́gẹ́ bí "ohun àmú-gbàyè nínú ìhun gbólóhùn nínú èyí tí ẹni tí à ń bá sọ̀rọ̀ ti ní láti mú ìtumọ̀ wá láti apá ibòmíràn nínú àyọkà. B.A.

2 Máa brainwash mi o.i. 3

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé, dandan kọ́ ni kí gbólóhùn àṣẹ, àpẹẹrẹ irú èyí tí ó wà ní (2) lókè yìí ni olùwà, síbẹ̀, ó jẹ́ àpẹẹrẹ ìgékúrú níbi tí a ti lè mọ olùwà gbólóhùn náà nípa wíwo gbólóhùn tó ṣáájú.

Ní èro Fontaine (2013), ìgékúrú yìí ni ó dàbí pé ó fẹ́ẹ̀ wúlò jù lọ nínú gbogbo ète ìṣewẹ́kú nítorí a máa ń ṣe àfihàn rẹ̀ nípa òye tí ó dá lórí àwọn fọ́nrán kan tí a fò. Nínú ìtúpalẹ̀ gbólóhùn, ìtumọ̀ tí a rí nínú gbólóhùn tí ìgékúrú ti jẹyọ náà ni ó wà bí a kò bá gé ọ̀rọ̀ kankan kúrú. Ẹ̀yà ìgékúrú mẹ́ta ni a tọ́ka sí nínú pépà yìí: ìgékúrú ọ̀rọ̀-orúkọ, ọ̀rọ̀ ìṣe àti awẹ́ gbólóhùn. Orúkọ àwọn ẹ̀yà ìgékúrú wọ̀nyí sọ àwọn fọ́nrán tí a gé kúrú.

**Ìgékúrú Ọ̀rọ̀-Orúkọ**

Ìgékúrú ọ̀rọ̀ orúkọ je eya ìgékúrú fún ọ̀rọ̀ orúkọ. Àpẹẹrẹ láti inú *Ó le kú:*

3. Kí ni Dọtun wí?
   (Ø) Kò sọ̀rọ̀, ó kàn ń wo àwòrán ni.  O.i 57

4. Hẹ̀ló
   Hẹ̀lóó
   Ta ni?
   Lọlá ni o.
   A, pẹ̀lẹ́ o, kín ni nǹkan?
   Ø kò burú rárá o.  O.i 72

Ìgékúrú ni a fihàn nípa lilo ami isofo ø nínú àwọn àpẹẹrẹ oke yìí. Ami (ø) ń fi àyè Dọ̀tun àti nǹkan hàn.

**Ìgékúrú Ọ̀rọ̀-Ìṣe**

Ẹ̀yà ìgékúrú yìí ń tọ́ka sí ìgékúrú àwọn fọ́nrán àpólà ìṣe. Àpólà-ìṣe tó jẹyọ ṣáájú máa ń fún èyí tí ó tẹ̀lé e ní ìtumọ̀ nígbà tí àwọn àbùdá ìṣe kò bá hàn nínú rẹ̀. B.A.

5. Ẹ jọ̀wọ́, níbo lẹ sùn?
(Ø) lọ́dọ̀ ọ̀rẹ́ mi obìnrin. O.i 10

A lè fún "lọ́dọ̀ ọ̀rẹ́ mi obìnrin" ní ìtumọ̀ pé ó dúró fún mo sùn lọ́dọ̀ ọ̀rẹ́ mi obìnrin.

## Ìgékúrú Awẹ́-gbólóhùn

Ìgékúrú nínú awẹ́-gbólóhùn ní ṣe pẹ̀lú ìgbésẹ̀ ìbéèrè nínú afọ̀ isọ̀rọ̀-ǹ-gbèsì. Èyí túmọ̀ sí pé ẹ̀yà méjì ni a lè tọ́ka sí: (a) Ìgékúrú oníbẹ́ẹ̀ni bẹ́ẹ̀kọ́ àti (b) Ìgékúrú onídáhùn àlàyé. B.A.

6. Àṣàkẹ́ ní, Ṣé ó lóun kò jó ni?
Dépò ní, Ẹn. (Ø: ó ní òun kò jó). O.i 2

7. Ọgbọ́n la máa dá si nítorí mo fẹ́ kí o wá rí mi lọ́la o.
A, ìyẹn á le díẹ̀ o.
Báwo? (Ø: ni ìyẹn á ṣe le díẹ̀). O.i 11

Gbólóhùn (6) jẹ́ àpẹẹrẹ ìgékúrú oníbẹ́ẹ̀ni bẹ́ẹ̀kọ́. 'Ẹn' tí ó jẹ́ ìdáhùn Dépò sí ìbéèrè Àṣàkẹ́ ní ìtumọ̀ kan náà pẹ̀lú bẹ́ẹ̀ni tí a lè fún ní ìtumọ̀ 'Ẹn (bẹ́ẹ̀ni) ó ní òun kò jó'. Gbólóhùn keje ní tirẹ̀ jẹ́ àpẹẹrẹ ìgékúrú onídáhùn àlàyé ní ibi tí ìbéèrè 'báwo' ti ń rétí ìdáhùn àlàyé. Ìgékúrú jẹ́ ìbátan ajẹmọ́-gírámà. A máa ń lò wọ́n láti so ọ̀rọ̀ àti àwọn ìhun pọ̀ yàtọ̀ fún síso ìtumọ̀ wọn pọ̀.

## Ìsopọ̀

Ìsopọ̀ jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ètò gírámà tí kò ní ohunkóhun ṣe pẹ̀lú ìhun àmọ́ tí à ń lò láti fi kún ìṣewẹ̀kú afọ̀. Àwọn fọ́nrán yìí, yálà wọ́n jẹ́ ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ tàbí apá kan àyọkà máa ń fi ìdí ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín awẹ́ gbólóhùn, gbólóhùn àti àyọkà hàn. Fọ́nrán àyọkà jẹ́ ète ìṣewẹ́kú tó ń ṣiṣẹ́ ìsopọ̀ nípa ìtumọ̀ wọn. Èyí túmọ̀ sí pé àwọn fúnra wọn ní ìtumọ̀, ìtumọ̀ wọn yìí ni ó ń jẹ́ kí á mọ ìwúlò àwọn fọ́nrán tó yí wọn ká. Wọ́n lè fi ìbátan wọn hàn pẹ̀lú àwọn gbólóhùn tó ṣáájú tàbí tẹ̀lé wọn. Bí a bá fi ojú ìṣewẹ́kú wò ó, ìsopọ̀ ni a lè rí gẹ́gẹ́ bí ìjẹyọ tẹ̀lẹ́-ń-tẹ̀lẹ́ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú afọ̀. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítórí pé àwọn gbólóhùn inú afọ̀ gbọ́dọ̀ tẹ̀lẹ́ ara wọn kí á tó lè so irú àwọn gbólóhùn bẹ́ẹ̀ pọ̀. Ohun tó jẹ ète yìí lógún ni fífi ìbáṣepọ̀ hàn láàárín àwọn fọ́nrán lìǹgúísíìkì tó jẹ yọ tẹ̀lé ara wọn.

Kì í se wí pé ète ìsopọ̀ kàn ń so gbólóhùn méjì pọ̀ nìkan, ó tún ń ṣàfihàn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú wọn lọ́nà tí yóò gbà ní ìtumọ̀. Àpẹẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀ tó ń ṣiṣẹ́ ìsopọ̀ ni *ṣùgbọ́n, àmọ́, tàbí, àti, nítorí, bákan náà* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí ọ̀rọ̀ ìsopọ̀ bá jẹ yọ ní ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn, a jẹ́ wí pé a lò wọ́n gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àkọ́sọ aṣewẹ́kú (Textual Theme) nínú ìtumọ̀ aṣewẹ́kú fún gbólóhùn. Èyí máa ń ṣiṣẹ́ láti ṣàfihàn ìbátán tó wà láàárín awẹ́-gbólóhùn kan àto òmíràn. Halliday àti Hasan (1976) pín ète ìsopọ̀ sí ẹ̀yà mẹ́rin: Ìsopọ̀ aláfikún, Ìsopọ̀ Ajarètí (a-já-ìrètí), Ìsopọ̀ Afìdíhàn (a-fi-ìdí-hàn) àti Ìsopọ̀ asàsìkò (a- sọ-àsìkò). Àwọn ọ̀rọ̀ atọ́nisọ̀nà wọn yàtọ̀, wọ́n sì máa ń fi ìbátan inú gbólóhùn hàn ní ọ̀nà tó yàtọ̀ látàrí ìtumọ̀ wọn gan an. A ó gbìnyànjú láti ṣàlayé àwọn ẹ̀yà wọ̀nyí ní ṣókí.

**Ìsopọ̀ Aláfikún**

Ìsopọ̀ aláfikún ń tọ́ka sí ẹ̀yà ìṣewẹ́kú tí ó máa ń farahàn nínú ìhun láti so gbólóhùn pọ̀. Ojúṣe rẹ̀ ni láti ṣe àfikún sí ìtumọ̀ tó wà nílẹ̀ nípa síso wọ́n pọ̀. Wọ́n máa ń sọ̀rọ̀ nípa àwọm fọ́nrán adádúró méjì tí ó jẹ yọ tẹ̀lẹ́-ń-tẹ̀lẹ́. Ẹ̀yà ìṣewẹ́kú yìí lè wáyé nípa ṣíṣe àgbéyẹ̀wò ìjọra tó wà láàrín ìtumọ̀ ohun tí à ń sọ lọ́wọ́ àti ohun tí ó ti kọjá. Àpẹẹrẹ ìsopọ̀ aláfikún nínú *Ó le kú* ni: *bẹ́ẹ̀ ni, àti, sí, àbí, àti pé, bẹ́ẹ̀ náà ni, síwajú sí i, ní àfikún abbl.* Bí àpẹẹrẹ:

8. Àjàní parí ìgò sítáòtù kan tán, ara rẹ̀ wálẹ̀ gbáà, orí rẹ̀ wá pé bí orí alájọ Ṣómólú tó fọdún mẹ́ta gbàjọ lọ́wọ́ ẹgbẹ̀rún ènìyàn láìkọrúkọ ẹnìkankan sílẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni kò sì ṣiwó san fẹ́nìkankan. O.i 1

9. hun, o tún dé o, oníkántan-kàntan. ọ́rọ̀ gidi là ń sọ lọ́wọ́ o. Òwe ni mo sì ń pa o. Bẹ́ẹ̀ náà ni, bí òwe bí òwe là á lùlù ògídìgbó o, ọlọ́gbọ́n ní í jó o ọ̀mọ̀ràn ní í mọ̀ ọ́n. O.i 3

10. Àjàní ní, Ìjàọlá, gbogbo ọ̀rọ̀ jọ́woni mà ti fọ́jú pọ́. Ìjàọlá ní ọ̀rọ̀ wo? Àní ọ̀rọ̀ Àṣàkẹ́ àti Lọlá. Fífọ́jú pọ̀ báwo? ṣèbí o ti sọ pé Àṣàkẹ́ làyò? Gbogbo ẹ̀ tún ti dàrú o, mo ti tọrùn bokùn lọ́nà méjèèjì. Fúnmi náà dá sí arọ̀ náà, ó ní, àbí o ti lọ mọ̀yá, mọ baba wọn ni?..... àti pe ṣe wọ́n ti wá sọ fún ọ pé ó rí bẹ́ẹ̀ ni ?. o.i 58-59

Gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ ìsopọ̀ tí a kọ ní àkohàn nínú àpẹẹrẹ 8,9,10 lókè yìí ni wọ́n ń ṣàfihàn ìsopọ̀ tó jẹ yọ nínú ìbátan àfikún kọ̀ọ̀kan. A lo 'bẹ́ẹ̀ ni' ni (8) láti so èrò inú gbólóhùn 'orí rẹ̀ wá pé bí orí alájọ Ṣómólú tó fọdún mẹ́ta gbàjọ lọ́wọ́ ẹgbẹ̀rún ènìyàn láìkọrúkọ ẹnìkankan sílẹ̀' pọ̀ mọ́ èrò tí ó jẹyọ nínú 'kò sì ṣiwó san fẹ́nìkankan' láti sọ èrò inú àwọn gbólóhùn méjéèjì di ẹyọ kan.

**Ìsopọ̀ Ajárètí**

Ìsopọ̀ ajárètí ni àwọn ìrètí tí kò lọ bí a ṣe lérò. Ìsopọ̀ tí ó farahàn nínú ìbátan ajárètí nípa ìlòdìsí ìrètí wa èyí tí tí ó wá láti ara ohun tí a mẹ́nubà ṣáájú. Ìrètí yìí lè wá láti inú afọ̀ tàbí àyọkà tàbí èrò olùsọ-olùgbọ́. Àpẹẹrẹ ìsopọ̀ ajárètí láti inú *Ó le kú* ni: *síbẹ̀, lóòótọ́, ṣùgbọ́n, nìkan, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, àti, pẹ̀lú abbl.* A ṣe àfihàn wọn nínú àwon àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

12. Ká sọ tòótọ́ n ò ní pẹ́ mọ ọkọ̀ wà o. Mo máa ń wo àwọn driver bí mo bá ti wọnú ọkọ̀ kan. Kò ṣòro láti wà kẹ̀! Kò ṣòro láti wà ná, bóbá ṣe pé tìyẹn ni. Àti bẹ̀rẹ̀ ló ṣòro. Síbẹ̀ ṣá o, kì í ṣe iṣẹ́ ìkánjú.... Èwo ló dé- towó ni, àbí taya, àbí tiṣẹ́, àbi ti mọ́tò? Èwo náà ni ò tó rò níbẹ̀? Ṣùgbọ́n kì í ṣe towó, Ọlọ́run ní í fún ni lówó, kì í ṣe ti mọ́tò, ẹ̀gbọ́n bàbá mi ti fún mi ní mọ́tò kan. Nipa taya, ó wà lọ́wọ́ Ọlọ́run.. o.i 73

13. Àṣàkẹ́ gba ọ̀rọ̀ mọ́ Àjàní lẹ́nu, ó ní, wò ó má tan ara rẹ jẹ. Kò sí ẹni tó ń ṣìmi lọ́nà. Mo sì ti ro ohun tí mò ń ṣe dáadáa. Bí o bá máa gbọ́ òtítọ́ , jẹ́ kí á parí ọ̀rọ̀ náà síbẹ̀. Lóòótọ́, mo ti fẹ́ràn rẹ rí, ṣùgbọ́n báyìí, kò sí ìfẹ́ kankan níbẹ̀ mọ́. O.i 76

àwọn ọ̀rọ̀ ìsopọ̀ tí a kọ ní àkọhàn nínú àwọn àpẹẹrẹ (12) àti (13) lókè yìí ni a lò láti so èrò tí ó wà ṣáájú nípa síso ìtumọ̀ wọn pọ̀. Ní àpẹẹrẹ (12), ìrètí gbólóhùn àkọ́kọ́ ni pé ọkọ̀ wíwà kò ṣòro. Lẹ́yìn èyí, ìsopọ̀ wáyé pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò ṣòro, síbẹ̀ kì í ṣe ohun tí à ń kánjú ṣe. ọ̀rọ̀ ìsopọ̀ *síbẹ̀* fihàn gbangba pé ìlòdìsí wà nínú èrò gbólóhùn náà, ọ̀rọ̀ yìí ni ó sì so ìtumọ̀ àwọn gbólóùn náà pọ̀.

## Ìsopọ́ Afìdíhàn

Ìsopọ́ afìdíhàn ní èrò Numan(1993:27) dúró fún ìdí tí ìṣẹ̀lẹ̀ fi ṣẹlẹ̀ àti àtunbọ̀tán rẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé awẹ́-gbólóhùn kan dúró fún ìdí tí ìṣẹ̀lẹ̀ kan fi ṣẹlẹ̀, nígbà tí apá tókù nínú gbólóhùn dúró fún àtunbọ̀tán ìṣẹ̀lẹ̀ náà. Ìbátan yìí ní i ṣe pẹ̀lú ìtumọ̀ tí òǹkàwé bá fún àyọkà láti yà àwọn gbólóhùn náà sọ́tọ̀. Bákan náà, ìbátan afìdíhàn lè sọ̀rọ̀ nípa àbájáde, ìdí àti ohun tí ó fa ìsopọ̀ ìṣewẹ́kú. Díẹ̀ lára àwọn ọ̀rọ̀ ìsopọ̀ afìdíhàn ni: *àti, ṣùgbọ́n, àmọ́, nítori/nítorí náà, nítorí ìdí èyí, lẹ́yìn náà, ní àkótán* abbl. Àpẹẹrẹ:

14. Àṣàkẹ́ dìde, ó tú aṣọ rẹ̀ ró, ó sì ń wé gèlè rẹ̀ náà, nítorí Àjàní ti tú gèlè náà lẹ́ẹ̀kan, ó ti ń fọwọ́ ra irun tí Àṣàkẹ́ sẹ̀sẹ̀ kó. O.i 5

15. Ọ̀rọ̀ yìí bá mi lẹ́kùfu ṣùgbọ́n n ó máa ronú sí i, ọ̀rọ̀ náà gba ìrònú nítorí ohun tí ẹ fẹ́ gan-an kò tí yé mi. O.i 27

*nítorí* nínú àpẹẹrẹ (14) ni òǹkọ̀wé lò láti so àwọn gbólóhùn méjèèjì pọ̀ nípa ṣíṣe àfihàn ìbátan afìdíhàn wọn. Awẹ́-gbólóhùn àkọ́kọ́ ni àtunbọ̀tán tó wáyé nítorí ipa tí ìṣe Àjàní ní lórí títú tí ó tú gèlè Àṣàkẹ́.

## Ìsopọ̀ Asàsìkò

Ìbátan asàsìkò máa ń sọ nípa tẹ̀lẹ́-ń-tẹ̀lẹ́ àsìkò ìṣẹ̀lẹ̀. Ó máa ń wáyé nígbà tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àyọkà bá bá ara wọn tan nípa àsìkò ìjẹyọ wọn. Ìbátan yìí dá lórí ọ̀gangan ibi tí ètò ìsafọ̀ bá dé nínú afọ̀. Ohun tí ó mú kí ẹ̀yà ìsopọ̀ yàtọ̀ àwọn tó kù ni pé ó lè jẹ yọ pẹ̀lú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń tọ́ka sí ọjọ́ iwájú. Àpẹẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀ tó ń tọ̀ka sí ìbátan yìí ni: *ní àkọ́kọ́, nígbà tó yá, láìpẹ́, lẹ́yìn náà, ṣáájú,lẹ́ẹ̀kan náà, ní ìparí* abbl. Ìsopọ̀ asàsìkò máa ń ṣàfihàn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tẹ̀lẹ́-ń-tẹ̀lẹ́ (sequential events) àti ìṣẹ̀lẹ̀ alájọwà (simultaneous events). ìṣẹ̀lẹ̀ tẹ̀lẹ́-ń-tẹ̀lẹ́ ni ìṣẹ̀lẹ̀ kan tí ó tẹ̀lé òmíràn nígbà tí ìṣẹ̀lẹ̀ alájọwà máa ń wáyé ní àkókò kan náà. Bí àpẹẹrẹ:

16 Láìpẹ́, onítọ̀ọ́jú aláìsàn ẹ̀ẹ̀kan pe Àṣàkẹ́. O.i 76

17 Bí kò bá fẹ́ gbà, o ó máa sọ ọ̀rọ̀ dídùn sí i létí. O máa kọ́ṣẹ́ sí lórí. Kẹ̀kẹ̀ bẹ́ẹ̀, ètò á tò. Lẹ́yìn náà, o ó wàá sọ fún un pé kó ó jẹ́ kí ẹ ṣe ìyàwó. O.i 13

A lo àwọn ọ̀rọ̀ ìsopọ̀ láti ṣàfihàn ìbásepọ̀ asàsìkò láàárín fọ́nrán méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ọ̀rọ̀ ìsopọ̀ tí a kọ lákọhàn nínú àpẹẹrẹ (16) àti (17) lókè fún wa ní ìṣewẹ́kú láàárín gbólóhùn sí àyọkà tí à ń ṣàgbéyẹ̀wò, eléyìí sì máa ń ran ìtumọ̀ lọ́wọ́.

## Ìgúnlẹ̀

Akíwùmí Ìṣọ̀lá yege nínú ìgbìnyànjú rẹ̀ láti jíṣẹ́ tó ní lọ́kàn fún àwọn òǹkàwé rẹ̀ nípa lílo àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ àti ìtumọ̀ tí ó ní ṣe pẹ̀lú kókó afọ̀. Ìlò ọ̀rọ̀ tí ó yẹ, àpólà àti gbólóhùn pẹ̀lú ìsopọ̀ tí ó wà láàárín won mú kí àyọkà náà ní ìtumọ̀ tó gúnrégé, tí gbogbo àwọn gbólóhùn náà sí gbé ìṣewẹ́kú jáde. Bí òǹkọ̀wé yìí ṣe lo èdè nínú ìwé ìtán àrosọ yìí wú ni lórí púpọ̀, èyí tí ó ṣe ìgbélárugẹ fún tíọ́rì gírámà ajẹmọ́lò tí a ṣàmúlò nínú pépà yìí. A lo tíọ́rì yìí láti wo ìlò èdè àti bí ó ti bá àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìwé náà mu. A fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé èdè wúlò fún fífi ìṣewẹ́kú hàn nínú afọ̀.

Ní ìparí, pépà yìí ti gbìnyànjú láti ṣàgbéyẹ̀wò àwọn ète ìṣewẹ́kú nínú ìwé ìtàm àròsọ *Ó le kú*. ìtúpalẹ̀ àwọn ète ìṣewẹ́kú wọ̀nyí tí ó jẹ yọ nínú ìwé náà fihàn pé àyọkà kan kò lè ní ìtumọ̀ láì sí ìbáṣepọ̀ láàárín àwọn fọ́nrán inú àyọka bẹ́ẹ̀. Nítorí ìdí èyí, kí àyọkà kan to lè ní ìṣewẹ́kú, àwọn ète ajẹmọ́-ẹ̀dá-èdè kọ̀ọ̀kan gbọdọ̀ so wọ́n pọ̀. Nítori náà, bí a bá gùn lé èrò Halliday (2014), àwọn ète ìṣewẹ́kú gbogbo tí a ṣàfihàn wọn nínú iṣẹ́ yìí ní ibátan pẹ̀lú afọ̀ nítorí pé wọ́n mú ki ìṣewẹ́kú wà. Ìṣewẹ́kú yìí ni ó dúró fún ète ajẹmọ́-ẹ̀dá-èdè tí ó so àyọkà yìí pọ̀ gẹ́gẹ́ bi ẹyọ kan.

**Èdè Ìperí tí a lò**

| | |
|---|---|
| *Àfikún | Circumstance |
| Akópa | Participants |
| Àyọkà | Text |
| *Ète ìṣewẹ́kú | Cohesive device |
| *Gírámà Ajẹmọ́-ìlò | Functional Grammar |
| Ìgékúrú | Ellipsis |
| *Ìlò asọ̀rírí | Experiential Function |
| *Ìlò afibáṣepọ̀-hàn | Interpersonal Function |
| *Ìlò ìṣewẹ́kú afọ̀ | Textual Function |
| Ìmọ̀ Ẹ̀dá-èdè | Linguistics |
| Ìṣewékú | Cohesion |
| Ìṣewẹ́kú ajẹmọ́-gírámà | Grammatical cohesion |
| Ìṣewẹ́kú ẹlẹ́yọ-ọ̀rọ̀ | Lexical cohesion |
| *ìṣẹ̀lẹ̀ | process |
| Ìsopọ̀ | Conjunction |
| *Ìsopọ̀ aláfikún | Additive conjunction |
| *ìsopọ̀ ajarètí | adversative conjunction |
| ìsopọ̀ afìdíhàn | causal conjunction |
| *ìsopọ̀ asàsìkò | temporal conjunction |
| Ìtọ́kasí | Reference |
| Ìtọ́kasí alórí | Endophoric Reference |
| Ìtọ́kasí aílàlórí | Exophoric Reference |
| *ọ̀rọ̀ àkọ́sọ-aṣewẹ́kú | Textual Theme |
| Sítáì | Style |

* Èdè-Ìperí tí a dálábàá

## Ìwé Ìtọ́kasí

Eggins, S. 2004. *Introduction to Systemic Functional Linguistics (2nd Edition).* London, UK: Continuum

Fontaine, L. 2013. *Analysing English Grammar: A Systemic-Functional Introduction.* New York:

Cambride University Press

Halliday, M. A. K. and Matthiessen, C. M. 2014. *An Introduction to Functional Grammar.* New York: Routledge

Halliday, M.A.K. and Hassan, P 1976. *Cohesion in English.* London: Longman.

Ìṣọ̀lá, A. 1974. *Ó le kú*. Ìbàdàn: Oxford University Press Limited.

Kafes, H. 2012. Lexical cohesion: an issue only in the foreign language? *English Language Teaching, 5, III,* pg. 83-94.

Nunan, D. 1993. *Introducing Discourse Analysis.* London: Penguin English.

Osisanwo, W. 2005. *Introduction to Discourse Analysis and pragmatics.* Lagos: Femulus Fetop Publishers.

Paltridge, B. 2000. *Making Sense of Discourse analysis*. Gold Coast, Queensland: Antipodean Educational Enterprises.

Peterson, C., & McCabe, A. (Eds.). 1991. *Developing narrative structure*. Hillsdale, NJ: Lawrence Erlbaum Associates.

Van Djik, A T. 1992. *Text and Context Explorations in the Semanticss and Pragmatics of Discourse*. London: Longman.